NEW YORK STATE | Office of the Medicaid Inspector General

# SỌ̀RỌ̀ SÍTA

# LÓRÍ ÌTÀNJẸ MEDICAID



**Fi ìtànjẹ Medicaid sùn, ìfiṣòfò tàbí àṣìlò sí Ibi-iṣẹ́ Ọ̀gá Àgbà ti Medicaid**

**Lọ́fẹ̀ẹ́: 877-87-FRAUD**

**877-873-7283**

**Ìtànjẹ Medicaid kìíṣe ọ̀ràn tí kò ní ẹnití a dálóró ó sì le wáyé pẹ̀lú ìfiṣòfò àti àṣìlò ní oríṣìí ọ̀nà. Nísàlẹ̀ ni àwọn àpẹrẹ díẹ̀ ti ìtànjẹ, ìfiṣòfò, àti àṣìlò Medicaid.**

| | |
|---|---|
| **Jíjí Ìdánimọ̀ Ìtọ́jú Ìlera** | Lílo àlàyé ìtọ́jú ìlera ẹlòmíràn láti fi gba owó, nkan, tàbí iṣẹ́. |
| **Ìdíyelé Iṣẹ́-àìṣe/Àìkópọ̀** | Ìdíyelé fún àwọn iṣẹ́ ni ipele tó lágbára tó si ju iṣẹ́ náà tí a pèsè tàbí kọsílẹ̀ lọ, tàbí lílo oríṣìí kóòdù fún iṣẹ́ tó yẹ kó jẹ́ kóodù kan ṣoṣo. |
| **Àwọn iṣẹ́ tàbí Ìfifúni Tí A Kò Ṣe** | Ìdíyelé fún àwọn iṣẹ́ tàbí ìfifúni tí a kò pèsè fún ẹnití ó yẹ, àwọn iṣẹ́ tí a kò kọsílẹ̀ dáradára, tabí méjèjì. |
| **Ìgbàpadà** | Bíbèrè tàbí gbígba owó (ojú-àánú tàbí owó àtọwọ́dọ́wọ́) nítorí ìdarísí ẹnìkan, ọjà, tàbí iṣẹ́ tí a le san lábẹ́ ètò Medicaid náà. |
| **Àwọn Ẹnití A Yọsọ́tọ̀** | Gbígbàsísẹ́ tàbí gbígbé iṣẹ́ fún ẹnikẹ́ni tí a yọsọ́tọ̀ tàbí àjọ fún ìpèsè nkan tàbí iṣẹ́ èyítí a ń san padà, ní tààrà tabí bẹ́ẹ̀kọ́, nípa èyíkéyìí ìtọ́jú ìlera ti Ìjọba Àpapọ̀ àti/tàbí ètò Medicaid ti Ìjọba Ìpínlẹ̀. |
| **Àṣìdarí Ògùn** | Sísọ ògun tí ko bá òfin mu fúnni, pínpín, àṣìlò, tàbí àpọ̀jù lílo àwọn ògùn tí a sọ fúnni. |
| **Ìtànjẹ Olùgbà** | Ìtànjẹ àmúyẹ, àpínlò káàdì, ìrajà dókítà, àti àṣìdarí ògùn. |
| **Dídára Ìtọ́jú/ Àṣìlò Aláìsàn/ Ìpatì** | Àṣìlò, pípatì, tàbí jíja àwọn aláìsàn Medicaid ní olè, èyí pẹ̀lú ṣíṣe àṣìlò àfojúrí àti ti ọpọlọ, ìdáduró àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera tó ṣe pàtàkì, tàbí ṣíṣe àìbìkítà láti pèsè itọ́jú tó péye tó sì tọ̀nà. |
| **Àṣìlò àti Ìtànjẹ Gbogbogbò** | Dídíyelé ní àwọn ọ̀nà tó kò péye pẹ̀lú ìṣàkóso ìṣúná-owó tó dára tàbi gbèdéke ti akọ́ṣẹ́mọṣẹ́; tàbí ìsanwó/ìdíyelé jẹ́ ìtànjẹ nígbàtí o bá mọ̀ọ́mọ̀ ṣé àti pé ó jẹ́ àṣìlò nígbàtí kò bá jẹ́ àmọ̀ọ́mọ̀ ṣe. |
| **Ìfiṣòfò** | Àlòjù àwọn ànfàní ti Medicaid, bíi ìwífún àwọn ògùn tí kò tọ̀nà tàbí tí kò wúlò, irinṣẹ́ àti ìfifúni ìtọ́jú ìlera, tàbí àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera. |

**Tí o bá furasí ìtànjẹ tàbí àṣìlò, kàn sí**

**Ibi-iṣẹ́ Ọ̀gá Àgbà ti Medicaid**

**877-87-FRAUD / 877-873-7283**

**www.omig.ny.gov/medicaid-fraud/file-allegation**